## Asayan Oro

Eworẹ wo alapata, bi ki o ku. Awodi wo gbin korọ, Kini ẹiyẹ oko yio fi igbin ṣe ? Ori l'o nişe ọda l'a yanmọ.

# ELETI OFE

A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJO

## Akiyesi Pataki

A fiwe yi ṣ e ikede si awọn Aşoju iwe irohin Eleti Ọfe kakiri agbaiye wipe ẹnikẹni ti ko ba fi owo ti o t i jẹ ranşẹ si wa, a o pe lejọ, ako si ni fi iwe irohin ranşẹ si enibẹ mọ.

VOL. XI No. 646. LAGOS. SATURDAY, OCTOBER 24 — OCTOBER 30, 1959. KOBỌ MEJI (2d)


# Itadogun Ku Si Dede Ojo Idibo Sunmo Dec 12, 1959.

EKO. Itadogun ku si dẹdẹ, ọjọ ẹlẹsin ko ọla. Igbimọ ijọba apapọşe tilẹ Nigeria ti şe ikede pe ni ọjọ 12th oşu December 1959 ni ao şe idibo gbogbogbo nile Nigeria.

Ni ọsẹ kini oşu November 1959, ni ao tu awọn igbimọ ti o ti nşe ijọba wa lati ọdun karun ka, ti ao si bẹrẹ eto lati yan awọn igbimo titun fun igbimọ apapọşe ti yio gba ominira fun gbogbo ilẹ Nigeria.

Awọn ẹgbẹ oşelu pupọ ni nwọn ti yan awọn ọmọ ẹgbẹ wọn sode ti nwọn si ti nkede orişirişi ileri ohun ti nwọn o şe fun ilọsiwaju ilẹ Nigeria, bi a ba dibo fun ọmọ ẹgbẹ wọn.

Pataki ninu awọn ẹgbẹ nwọnyi ni ẹgbẹ Action Group, ti a npe ni Afẹnifẹre. Ẹgbẹ N. C. N. C, ti a npe ni ẹgbẹ Alakukọ.

„ N, P. C. t i a npe
„ ni ẹgbẹ Olomi ati N. E. P. U., ti a npe ni ẹgbẹ Onirawọ l'Oke Ọya ati ọpọlọpọ ẹgbẹ miran titun lorişirişi ni o yọju s'ode.


# Nigeria Ports Authority

## Invitation To Tender

Tenders are invited by the Nigerian Ports Authority for the purchase of the under-mentiond scrap materials:-

| LOT NO. | LOCATION | DESCRIPTION |
|---|---|---|
| 1 | Port Harcourt Dockyard | Approximately 40 tons of Iron and Steel Scrap |
| 2 | do | 50 Unserviceable Batteries. |
| 3 | do | 50 Empty 45 Gallon Oil Drums |
| 4 | do | 80 Empty 5- Gallon Paint Drums |

2. The above items may be inspected on application to the Senior Stores Officer, Port Harcourt Dockyard, between the hours of 8 a.m. to 12 nood and 1. 30 p.m. to 4.30 p.m. not later than 30th October, 1959.

3. Tenders should be enclosed in sealed envelopes marked "Confidential Tender for Scrap" and should be addressed to the Secretary, Nigerian Ports Authority, Private, Mail Bag 2588, Lagos so as to reach him not later than Thursday, 5th November 1959. Late tenders will not be considered.

4. The successful tenderers in each case will be required to remove the materials at his own expense within 21 days of acceptance of his tender.

5. The Authority do not bind themselves to accept the highest or any tender.

A. R. CORDON

Secretary to the Authority.

N. P. A. Notice No. 351.

14th October, 1959.


## AWOLOWO TAJO DE EKUTE ILE PARAMO



Oloye Awolọwọ ti o ti ngbe ọkọ ofurufu rẹ fo lọ kakiri lati ma sọrọ ibo ti awọn ara ilu Onitsha şe igbimọ le lori wipe awọn ko fẹ ri ọkọ ofurufu rẹ ni Onitsha, ko gbọdọ da iwe kan silẹ ko si gbọdọ balẹ si ibẹ pẹlu.

Bakanna ni a tun gbọ wipe, ọkọ ofurufu rẹ ko gbọdọ balẹ si Aba, agbọ wipe ọkọ na balẹ tan o tun dara si.

Awọn ara ilu Aba tilẹ nşe igbimọ lori iru ẹjọ to yẹ ki nwọn ba Oloye Awolọwọ ro. Nisisiyi Awolọwọ lọ, o si pada bọ, eyi fi han pe ọmọ Akin ni işe. Tani ọpọlọ ndẹru ba, tani abuke ngbakuru mo, ẹniti a ba ta ki a fi ra atupa, o ni on a j i tanna w o loru. Oloye Awolowo ti lo oko ofurufu tirẹ, ẹniti ko dunmọ ko gbọdọ wi.

## Igbimo Ilu Aba Fe pe Awolowo Lejo

ABA Awon igbimo ilu Aba ngbero lati pe Oloye Awolowo lejo si kotu nitoripe awon ti kilo fun Oloye yi wipe oko oferufu re ko gbodo bale ni ilu won, sugbon o gboju-gba ya, o bale sibiti nwon gbe ti egba bolu ni ilu Aba.

A gbo lenu awon oleFofo wa kan wipe Oloye Awolowo ti toro gafara lodo Oloye S.L. Akintola wipe ki o fun oun ni ase lati ma fo loju sanma, o si ti gba iwe ase dani.

Nitoribe, ko si ofin kan ti o le di lowo lati rin loju sanmo. Awon igbimo Ilu Aba so wipe ofin kejo ti igbimo ilu Aba ni awon yio fi ba Awolowo sejo.

E MA KA
IWE IROHIN
ELETI-OFE
LOSOSE
O KUN FUN
IROHIN ALADUN





Wholesale Distributors:
Badejo Stores, 5 Olotogun St., Lagos
Dayo Development Co., 161 Victoria St., Lagos
Joey Ola Fajumolu & Bros., 21 Balogun St. West, Lagos
Nwosu Bros. Stores, 24 Asa Rd., Aba
Ebele Egbunam Stores, 38 Church Road, Kano
Olasinboh Business Enterprise, P.O. Box 53, Kano.
Ezenweaku Trading Stores 48 Aggrey Road, Port Harcourt.

PHILIPS (W.A.) LTD. P.M.B. 2023 Lagos





No 152

# Federal Election 1959

## Nomination Of Candidates

Shortly after His Excellency the Governor-General has appointed a date for the forthcoming Federal Election, the Electoral Officer in each constituency will publish a notice which will give details with regard to the nomination of candidates including the lawest date by which nomination papers must be delivered to him.

In accordance with Regulation 44 of the Elections (House of Representatives) Regulations 1958 the Electoral Officer must fix the closing date for nominations on a day not later than the fourteenth day before polling day. In the majority of constituencies the Electoral Officer will probably fix the closing date twenty-one days before polling day. In a few constituencies where distances are great and communications difficult the date may be brought forward earlier than this, but in no case will it be earlier than twenty-eight days before polling day.

At least seven days clear notice will be giving in each constituency of the closing date for nominations and nomination papers can be delivered to the Electoral Officer any time between the publication of the notice and the final date fixed by him.

R. E. WRAITH
CHAIRMAN
ELECTORAL COMMISSION

E DIBO FUN OPE

## Itan Ajapa Ati Ekun

Apa IV

Lati Ọwọ Ẹsọ

Nigbati ọba dele, ọrọ na bẹrẹ si ṣe e ni kayefi, o ranṣẹ pe awọn igbimọ rẹ, o pe Erin, Ẹfọn, Gidigidi, Ira, Ijakumọ, Koriko, Egbin, Ẹkiri, Inaki, Arọni Ijimere ati awọn ẹranko nlanla jọ o bere lọwọ wọn nipa Alijanu ti o ma nwa da ọja ru ni ọjọ marunmarun yi, ẹnikẹni ti o ba mọ ọna ti a le fi mu alij nu na on ọba ylo da ile ati ọna on si meji on yio fifun oluwa rẹ.

ni Ẹkun ti gbọ nipa ọrọ ẹbun yi ara rẹ bu mọ aṣọ o wi fun ọba pe Kabiyesi agbalagba ki wa lọja ki ori ọmo titun wọ. Balogun ni mo jẹ nilu yi nko' si le laju mi silẹ ki ẹnikan ma ba aiye jẹ ki a si so pe a ko mo ohun ti o nlo Nigbati oja daru, ti on gbo bẹ pe oja daru mo sare lo si oja ẹniti mo koko ri to nje oja ni Ajapa. Ọba bere wipe njẹ o da o loju wipe o ri Ajapa o dahun pe, hẹn.

Ọba paṣẹ wipe ki nwon lo pe Ajapa wa. Nigbati awon iko oba de odo Ajapa nwon jiṣẹ oba fun u, Ajapa ṣe won ni alejo nwon koko ti fẹ ko ṣugbon nwon ri pe ẹwa oṣoṣo ni o nse lori ina nwon duro jẹ ninu ẹwa na nwon fi aṣiri pipe ti oba pe han

Ajapa so fun awon iko pe ki nwon ma niṣo on mbo Nigbati o de afin oba, oba bere pe kini ohun ti o mo nipa ti alijanu to nda oja ru yi Ajapa so 2po ifa rẹ kalẹ, bi o ti da beni o ri Ọbara Olo-ogun o wi fun oba wipe, Ha eni nla lo nṣe ohun, ẹni ọran ṣoju rẹ! lo ma tan ọrọ Ijoye ilu kan lo, ṣiṣẹ, i'oye na kọla si gbogbo ara rẹ e ni tubọmu, o si lẹsẹ mẹrin.

Ẹkun bere pe se ko nṣe on bi ? Ajapa tun wi fun ọba pe, bi a ba dele ijoye yi ao ri awon ẹru ti o ko ni ọja. Nigbana ni ọba ṣe waranti lati lọ fi wo ile Ẹkun nwon ba gbogbo ẹru ti o ko ni oja ni won ba gbe Ẹkun ju sinu tubu.

Ẹ ma ka iwe irohin Eleti-Ọfe, ẹ o gbo bi owo ṣe tẹ Ajapa.

# Gomina Agba Tile Ghana



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Alagba Earl of Listowel, ti o jẹ Gomina agba (Governor General) fun ilẹ Ghana, ẹni adọta ọdun, o si ṣiṣẹ pupọ labẹ Ijọba ilu Gẹsi.

Ni odun 1941 si 1944, on ni serekode fun igbimọ Labour Party. Osiṣẹ Sẹkitẹri labẹ ijọba ilẹ India ninu ọdun 1947, on ni sẹkiteri fun ile Burma ni 1948.

O kọwe ni Eton and Balliol College ni Oxford, o si ti sise Postmaster ri, o fi igba kan ṣe Minister Agbẹ ati Apẹja.

## Ibere Ati Idahun

Ọkan ninu awọn Olukọ ilewe Ọlọpolọ lo mbere lọwọ awọn ọmọ ilewe bayi wipe:-

Olukọ- Ojo, sọ fun wa, awọn wo ni alaya pupọ nilẹ Nigeria.

Ẹnikini- Awọn Yoruba ! nitoripe awọn lo nfẹ obinrin pupọ.

NEXT !

Ẹnikeji- Awọn Imale ! nitoripe Mẹẹ ni Ọlọrun wi. Next

Ẹnikẹta- Awọn Igbomina! nitoripe awọn lo nfi onjẹ ati obinrin ṣe alejo. Next.

Ẹnikẹrin- Awọn ọba ilẹ Nigeria ! nitoripe oba' 'ti iyawo rẹ ba kere l'o nni mẹwa Good !

**E MA KA**

IWE IROHIN

**ELETI-OFE**

LỌSỌSẸ

O KUN FUN

IROHIN ALADUN

## AWỌN AGOKE MEJI JALULẸ, NWỌN DERO ỌRUN

Katmandu. A gbo irohi wipe awọn obinrin meji ti nwọn jẹ goke-goke ti ko si oke ti nwọn kole gun, nwọn lọ gun ori oke nla kan ti nwọn npe ni Himalya nilẹ India, ekini-ekeji nwon ati awọn amọna wọn jafọ, nwọn si ku bamu-bamu.

Ẹnikini ni Iyafin C. Kogan,eni ogoji ọdun, on si ni aṣiwaju gbogbo awọn obinrin ti o ngun oke, enikeji ni Iyafin M. C. Van dastratten, eni odun mẹrindilogbon.

Ohun ti agbo wipe o gbe awọn obinrin na dide ni wipe, ko si ohun ti ọkunrin ṣe ti obinrin ko le se. Fun opolopo odun ni a ti gbo wipe ko si eniti o le gun oke deṣonṣo ori oke Himalya nitoripe ko si oke kan ti ga to laiye yi julo.

Sugbon ni odun to koja lo, a gbo wipe awọn agoke meji kan gun ori oke Himalya yi, nwọn de ṣonṣo ori rẹ, nwọn si ya aworan, ogunlọgọ awọn ara ilẹ India si jẹri si pe, nwọn ri ohun meji kan ti o da bi era ti o nrin ni ṣonṣo ori oke na.

Ni wọn igbati ọkunrin ti le ṣe eyi, obinrin na nilati le see. Eyi ni a gbọ pe o gbe awọn obinrin mejeji na dide.

## OFIN IDIBO TI O YẸ K'A MỌ

1\. Ẹnikẹni ti o ba fun enia ni owo, onjẹ tabi ọti nitoriki nwọn le dibo fun u oluwarẹ lu ofin ijọba.

Ẹnikẹni ti o ba fi agbara mu enia lati dibo, tabi o dẹruba wọn, tabi o lo ẹsẹ gigun, nitoriki nwọn le dibo fuọ u oluwarẹ daran ijọba.

3\. Ẹnikẹni lo ni anfani lati lo gbọ ọrọ idibo nibti nwọn gbe nsọ ọ, ṣugbọn ẹnikanẓko gbọdọ huwa ja nduku, bẹni nwọn ko gbọdọ kọ enia lati ṣe jagidi jagan ki nwọn ba le da ipade na ru, ẹnikẹni ko si gbọdọ mu ohun ija dani.

Wo yoku loju ewe karun

HINDU SAKKARA'S

Religious Art Jewelleries



Perfumes, Charms, Mohammedan charms, Amulets, Vedic Prayers Kawachas, [illegible] Reproductions of Hindu Gods in the Jewelleries.

Enclose 4/- Postal order by Air Mail for Catalogues and Literature.

HINDU SANKARA, 431 Archway Road, London, N.6, England

No 150

# ELETI - OFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI L'EJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS
25, Kosoko Street, Lagos.
P. O. Box 468

CABLES & TELEGRAM
"ELETI - ỌFẸ LAGOS"
Phone 23370

VOL. XI. NO. 646 SATURDAY OCT. 24 - OCT. 30 1959

## Owuye Asoro So Bi Oro...

Ọrọ l'o pa ẹnikan lana. Gẹgẹbi oye ti a nri lojojumọ lode aiye yi, ọmọ enia nlati ma kọ ẹ k ọ ninu rẹ, nitoripe bi enia ba ṣi ọrọ sọ, yala nipa kikọ sinu iwe tabi sisọ jade lẹnu, ti ẹniti ọrọ na ba wi ba ti le ri awọn enia ti yio jẹri si gbolohun ọrọ ti a wipe o jẹ aṣisọ yi, egele gbe ẹniti sọ orọ na, bi awọn ba mu de iwaju ijoko nibiti tijolo gbe dunlẹ. Iyẹn ni ori-atẹ idajọ ni Kotu.

Bi ẹnyin ọkawe wa ba nṣe akiyesi Irohin ti ẹ nri ka lorekore ninu iwe irohin wipe lagbaja pe tamẹdo lẹjọ fun aṣisọ ọrọ ti o mu ibani lorukọ-jẹ dani tabi eyiti o ko abuku ba enia nipa ipo ti oluwarẹ wa wipe ki adajọ ba wọn gba ogidi-nleje owo ribiribi lọwọ ẹniti a pe lẹjọ na, fun ifi tun orukọ ṣe.

Njẹ, ẹnyin enia wa, ọrọ owe awọn baba wa ti a fi ṣe akọle wos'ka wa ọsẹ yi ko ha nṣe otitọ baun ? "Owuyẹ, aṣoro sọ bi ọrọ, ọrọ l'opa ẹnikan lana".

## E Dibo Fun Ope

# Federal Election 1959

## Allocation Of Symbols

In accordance with Regulation 141 of the Elections (House of Representative) Regulations 1959 the following symbols have been registered on behalf of the Parties concerned in the Register of symbols kept by the Electoral Commission :-

| | |
|---|---|
| ACTION GROUP | Palm Tree. |
| National Council of Nigeria & Cameroons | Cock. |
| Northern Peoples Congress | Hoe |
| Northern Elements Progressive Union, | 5-Pointed Star |
| Democratic Party of Nigeria & Cameroons. | Elephant |
| United Muslim Party | Torchlight |
| National Emancipation League (Ijebu-Ode) | TilleyLamp |
| Nigeria Peasants Party | Whiteman's Portrait. |
| Niger Delta Congress | Fish in Triangle. |
| U. M. B. C. (independent) | Nerzit Hunter. |
| Igala Divistonal Union N. P. C. Alliance | Lion |
| Ijebu Parapo Party | Key |
| Igbira Tribal Union | Arrow |
| Igbirra Tribal Union/ N. P. C.Alliance | Tricolour Flag |
| Oshun United Party | Crops in Basket |
| Egbe Omo Ibile Akure Ati Agbegbe | Alarm Clock. |

The Electoral Commission has made the following symbols available for use by independent candidates :-

Bicycle, Scissors, Sewing Mechine, Motor Car, Horse, Hand, Saw, Chair, Gramophone and Matchet.

### ERE BỌLU NILU KANO

KANO. Nibi ere bọlu afẹsẹgba ti awọn ọlọpa ilu Kano ṣpẹlu ti ilu Katsina. (awọn ọlọpa ibilẹ ni a wi o) Ọlọpa ti Kano l'o gbori lọwọ ti Katsina. Ti Kano gba meji wọle, Katsina ọkan.

Kano la Katsina mọlẹ Kenge !






## IRỌ NI ẸGBẸ ALAKUKO PA

ILE-IFẸ. A ti ngbo irohin kiri wipe awon igbimo ile Ife dide si Alaiyeluwa oba Oni ile Ifẹ wipe, ki o fi ori oye oba silẹ tabi ki o jade kuro ni ilu patapata.

Alaiye ọba Ifẹ sọ wipe, ki awon mase gba ọrọ, na gbo iro fun-fun balawu ni. Ko si enikan tabi igbimọ kan ti o ba on so pe ki on fi ori oye silẹ. On si ropẹ ara irọ ti awon Alakuko ma ngbe lankẹ rẹ kiri nitori akoko idibo ba mbọ bayi nini, nwon ma nse eyi nitori ki okan awon enia le yi pada.

Lojo aipe yi ni Alaiyeluwa ọba Oni Ifẹ se ipade pelu awon oloye re ninu afin Ati-ole. Ẹgbẹ Alakukọ ẹ ye irọ pa gudugudu bonin-bonin, eni to ba wu ki o be.

## Iwa Janduku Be Sile Ni Sokoto

SOKOTO. Ni ilu Sokoto nibiti Alhaji, Sir Ahmadu Bello Sardauna, olori awọn Oselu ni Oke-Oya ati baba egbe N.P.C. ngbe ni a gbọ wipe, awon ti bere iwa janduku si awọn egbe Action Group. Fun bi ọsẹ meji sẹhin.

Awọn janduku nwọnyi lọ ki Ọkunrin kan ti o njẹ Malam Adamu Kamba ara ilu Argungu ti o si jẹ omo ẹgbẹ Action Group mọlẹ nwon si gbe ju si itimole, fun iwọn ogunjo lo fi wa ninu tubu, nitoripe o kọ fun Alikali ki o ma ṣe ejo on.

Ohun ti a gbọ wipe o da rogbodiyan yi silẹ ni wipe Adamu Kamba lo fi ejo wolewole kan sun oyinbo Ajẹlẹ pe o gba owo abẹtẹlẹ ni ilu Argungu, ni wọn ba yi oro na le Adamu Kamba lori wipe o faijẹ Ọlọpa o nfẹ ṣe iṣẹ olọpa.

## HOGAN BASSEY YIO TUN BẸRẸ IJA



LONDON. Ọgbeni Hogan Kid Bassey ti o ti fi igba kan je oye olori gbogbo awon akanse ti o wa ni gbogbo aiye, ti asiko na si tun yi pada ti oye na fi ni lati bo kuro lori re.

Gbukẹ ni a gbọ, nitori pe Ọgbẹni Bassey ti o fi eju gba ogbe n-bi ere ese ija ni Los Angeles nile Amerika, eyi ti o gba oye kuro lori re, ti o si gbo wipe, o ti nsiran lo ise nfe ja ija olokiki kan ti nwon npe ni Empire Title.

Ẹniti o fẹ ba Ọgbeni Bassey koju ija na ni ọkunrin kan, enia dudu ara ilẹ Trinidad ni agbegbe ilẹ Wesingisi (West Indies) eniti o ti woya ija nigba meji tele pelu Bassey ti o si fi eja ri emimọ lọjọ ti Bassey lo ti eleta si ọkunrin na lara, o gboju gbaiya o tun pe Bassey nija.

## OFIN IDIBO TI O YẸ K'A MỌ

(O bere loju ewe keta)

4. Lọjọ idibo, ẹnikan ko gbọdọ di enikeji lowọ lati dibo nitori igba ese si ile idibo a ko gbọdọ ko enia pe lagbaja ni ki o dibo fun, a ko gbodo sọ ede ena tabi ki nwon ma lo ami ẹgbẹ wọn bi Ope, ati Akukọ nwon ko si gbodọ pe apejọ, beni nwon ko si gbodo pe apeju, beni nwon ko gbodo se ikede, gbogbo iwonyi ni a ko gbodo ṣe lojo idibo.

5. Ẹnikẹni ko gbodo dibo lemeji, bẹni eniti ko to ko gbodo dibo nwon ko si gbodo fi oruko ẹlomiran dibo.



### OMỌ TI O LỌ 'KỌ IṢẸ ALUFA FI OWO BABA RẸ GBAGI
(Lati Owọ Eṣọ)

Nigbati Oyinbo gbe orişirişi işẹ de silẹ Nigeria awon enia dedu ko tun fẹ şe işẹ oko riro mọ, idera ni olukuluku enia nwa lori. Ka şe işẹ diẹ, kagba owo pupo gẹgẹbi işẹ Lebira, Kuku ọmọ ẹdọ oyinbo, Akọwe, Işe Akangba, işẹ gbagimolẹ işẹ Reluwe. Eyiti olowo lori ju ni akoko na ni işẹ Alufa ojişẹ Olorun (Minister of God).

Ọmọde kan ti o njẹ Jide lọ ka iwe meta, o si le sọ ede Gesi daradara, ni baba rẹ ran lọ silu Oyinbo lati lọ kawe meji si lohun, ki o si lọ şe idanwo fun işẹ Alufa ki o to ma bọ wa sile. Nigbati Jide de ilu Oyinbo obinrin oyinbo lo berẹ si gbe kiri.

Ninu idanwo işẹ Alufa ni akoko na, oluwarẹ ni lati gbọ ede awon ara Rome (Latin) ki o to le yege işẹ na. Baba Jide ko mọ pe obinrin ni ọmọ rẹ nko kakiri, ko lọ silewe deedee ko si tilẹ ranti lati şe idanwo işe idanwo Alufa. Nigbati o şe, baba rẹ ranşẹ si wipe bi o ba ti yege ninu idanwo işẹ Alufa, ki o tete mabọ nile, nitori awon Ijọ ti yio ma şişẹ larin won ti nreti rẹ.

Wo yoku loju ewe keje

# Olotu Ijoba Ghana nilu Oyinbo



Aworan ti a nwo yi ni Dr. Kwame Nkumah, nigbati o gunlẹ silu Oyinbo, ti o lọ ba Alaiyeluwa Ọba obinrin ilu Gẹsi ni Balmoral Castle, gẹgẹbi ajọsọ ọrọ won, nipa wiwa bọ ilẹ Ghana wo ti ọba Gẹsi na ni on ko ni le wa bẹ won wo ni ọdun 1960 gẹgẹbi on ti şeleri, nitoripe on nşe ireti omo titun. Ki Ọlọrun şe asokalẹ anfani o. Amin.

## OBA SHAGAMU ATI OMO RE



Awon ti a nwo ninu aworan yi ni Ologbe Alaiyeluwa Akarigbo, Ọba Şagamu ati Ọmoba Adedoyin ti o wa ni ipo Alaşẹ (Speaker) igbimọ ijoba Iwo-Orun.

Kere o !

A ni orişirişi ogun German to şẹşẹ de, fun oniruru aisan tọkunrin tobinirn. Tete wa ra tirẹ ki o to tan.

J. A. AJAO
BROTHERS
MEDICINE STORES
7. Egerton Road Lagos

SICK? AFFLICTED? Crippled? Write for free List of Vital Books on Divine Healing, also Helpful Information and Prayer to:- Gordon Cove, Brierley Hill, Staffordshire, England.

"The English Association of Accountants & Auditors. The English Association of Estate Agents & Valuers. The English Association of Secretaries. Founded 1941. Membership on Professional Experience (Give Details) or Exams passed. 9, Charles St. Newport, Mon. Eng".

### ṢỌJA KAN PA ERIN MEJI NI ANAM

Irohin de lati ọdọ awọn enia pe ajanaku meji kan nlanla sina wọ inu oko, o ba awọn ebe isu jẹ, o lẹ agbado mọlẹ, o fi ẹsẹ ja ẹwe eree, nwon ko si to lati ko erin na loju, nwọn wa lo rohin fun awon oyinbo şoja ni Ẹnugu.

Nwon yan ọgagun kan Leiut. D.J. Stewart Smith lọ si ilu Anam na Ọkan ninu awọn Erin na tobi o si jẹ akọ ọwo ija rẹ gborin jojo ehin kan şoşo lo si ni pẹlu bi a ba

Wo yoku loju ewe kejọ

# Ijoye Kan Pa Ere Nla

MBAISE. Ijoye kan dide ni ilu Mbaise mu ada, o wọ inu igbo lọ lati pa oko fun awọn ewurẹ rẹ. Bi o ti npako lọwọ, lo gbe oju soke o si ri akọ ere kan ti o nbọ, o si pa ejo na, ejo ti a wiyi nigbati nwọn diwọn rẹ, o jẹ ọgbọn ẹsẹ. Ilu Ibiti nwọn ti pa ejo ti a wi yi jẹ agbegbe ilẹ Owerri.

A gbọ wipe nwọn gbe ejo na lọ si ọdọ Ajẹlẹ kekere, Ajẹlẹ na wa ranṣẹ pe awọn Ijoye ilu Oweri, o ni ki nwọn lọ pin ejo na larin ara wọn, nwọn sọ pe awọn ba ẹnyin ninu ejo na ati wipe ejo na ti ṣe jamba pupọ ki ọwọ to tẹ.



## ÌGBÌMỌ̀ ILE KIKỌ

Igbimọ ti nkọle ni Ipinlẹ Iwọ Ôrun ti a da silẹ labẹ ofin kejila ti ọdun 1958 lati mã ṣe eto iṣẹ ọwọ ati itẹsiwaju ti bẹrẹ iṣẹ rẹ. Igbimọ yi ti ṣe eto ọdun meji fun iṣẹ itẹsiwaju ati ile kikọ eyiti a ti pese oke sheta... ati abọ poun fun. Igbimọ yi yio kọ awọn ile ti o dara ti o si ni agbara lori ilẹ ti a ya, yio si ta wọn fun awọn enia; yio si mã ya awọn enia ti o ba tọsi lowo, ti nwọn ba fẹ kọ ile lori ilẹ ti wọn. Owo ... ma pari ile yi yio bẹrẹ lati ẹgbẹrun de ẹgbẹdogun poun nisisiyi, ṣugbọn a le kọ ile ti owo rẹ ko to eyi ni ọjọ iwaju. A ti bẹrẹ ile-kikọ ni Bodija ni ilu Ibadan, a si ti bẹrẹ si ṣiṣẹ lori ilẹ ti a ti yasọtọ fun eto yi ni Ikeja. Ni Ikeja Igbimọ yi nṣ'iṣẹ lori ile iṣẹ ọwọ ati ile gbigbe. Awọn enia le ri imọran gba lori ilẹ ati ile kikọ ni ile iṣẹ Igbimọ yi ni Ikeja. A ṣe awọn eto yi fun anfani awọn enia ti ngbe Ipinlẹ Iwọ Ôrun nikan. Awọn enia le ri iwe-alaye lori eto yi gba lọfẹ lati ọwọ awọn ọga ile iṣẹ wọnyi:—

The General Manager,
Western Region Housing Corporation,
P.O. Box 867, Ibadan.

Officer in charge, Ikeja Branch Office, Western Region Housing Corporation,
Private Mail Bag No. 1016, Ikeja.

Offices of the Information Division, Ministry of Home Affairs and Midwest Affairs throughout the Region, Regional Library, New Court Road, Ibadan, and the British Council Library, New Court Road, Ibadan.

Ile Iṣẹ ti nkede Iṣẹ Ijọba Iwọ Ôrun Nàìjíríà l'ó gbe ọrọ yi jade.

# Omo Ti O Lo Ko Ise Alufa Fi Owo Baba Re Gbagi

O bẹrẹ lojo ewe kẹfa

Bi o ti gbọ oro yi, o ranṣẹ si baba rẹ pe, on yio de si Eko nipari oṣu. Nitotọ, o de, gbogbo enia si pade rẹ. Ni alẹ ọjọ Saturday ti o tele, ni baba rẹ se ase repete, o si pe gbogbo enia sibẹ lati wa gbọ bi ọmọ on ti gbo ede Latin to. Alufa titun na joko nipẹkun Tabili nihin, baba rẹ si jẹko koju si lọhun.

Nigbati nwon yo tan, baba Jide ba ijoko na sọrọ, o ni ki nwon dakẹ lati gbọ bi ọmọ on ti gbọ Latin. O gbe sibi ijẹun soke, o wipe. ọmọ iwọ ti lọ ko iṣẹ ojiṣẹ Ọlọrun nilu Oyinbo, iwọ si ti yege, nje sọ fun wa ki a gbọ, bawo ni nwon ti npe sibi yi ni ede Latin?.

O dide o wipe "It is called Spoon-abus" gbogbo awọn B. A. ati awon L. L. B. ati awọn D. Ph to wa ni ijoko wo ara won loju, nwon rerin, nwon si patẹwọ. Baba rẹ tun gbe awo pẹrẹsẹ soke. O tun wipe, ọmọ eyi nkọ kini nwon ti npe e ni ede Latin? Plate-abus.

Gbogbo awon enia tun bo lọ kulin. Baba rẹ tun gbe ọbẹ soke o wipe eyi nkọ, ọmọ mi, kini nwon ti npe ni ede Latin? O dahun wipe, Knife-abus.

Nigbana ni baba rẹ wa sọ fun pe, bi o ba jẹ wipe abus lo npari gbogbo ọrọ Latin, bere gbe Knife-abus ki o si lo si Farm-abus ki o si maṣẹ fun Belly-abus.

## IRỌ NI ẸGBẸ ALAKUKỌ PA.

ENUGU. Awon ọmọ ogun 1st Batalia dide larin ọsẹ yi lọ si ilu Uyo lati lọ dana wo nipa ohun ti nwon ti nkọ nipa iṣẹ jagun-jagun.

Nwon o de awon ilu bi Uyo, Annang Umuahia, ati agbegbe Oweri. Lasiko ti nwon lọ dana wo na, nwon o jo yida igboro ilu Uyo, Nung, Udoe, Oron, Eket, Abak, Opobo, Itu Aro-Chuku ati Okigwi.
Idi re ti awon soja ṣe fẹ yan agbegbe ibẹ ni wipe. ki awon ara agbegbe na le mọ bi iṣẹ soja ti dun ti o si larinrin to,

Iṣe soja dun,
O dun o larinrin,
Iṣe soja dun
O dun o larinrin.

## KO ṢEKU KO ṢẸIYẸ AJAWU

Lati Ọwọ R. Popoola

Nigba kan Aguntan kan wa ti o bi ọmọ meje ni ọjọ kan, adan fẹ lọ lati ki ana rẹ ti o ngbe ọna jijin rere o lọ sọdọ Aguntan o si bẹ pe ki o jẹki kan ninu awọn ọmọ rẹ ran on li ẹru, li akọkọ agutan ko ṣugbọn abikẹhin rẹ sọ pe on fẹ mọ ilu lọ, nitorina o bẹ iya rẹ pe ki o jẹ ki on lọ pẹlu Adan.

Nikẹhin aguntan gba fun u, ṣugbon ko de inu rẹ, nitorina li owuro ojo keji n'gbati ilẹ mo, adan ati omo agutan abikẹhin fi ẹsẹ le ona ile ana adan. Ọmo Aguntan si mu iwo omi adan. Nigbati nwon de idaji ona, adan so fun omo aguntan pe ki o fi iwo na pamo si abẹ igi aparun kan kete ti adan si dele ana rẹ, o ran omo aguntan pada lati lo mu iwo na wa. Nigbati omo aguntan kan lo tan, ana adan gbe onjẹ wa, o si jẹ gbogbo rẹ tan laifi ohunkohun silẹ fun omo aguntan lati jẹ ti o ba pada de.

Nigbati ọmọ aguntan de, adan ni A, o ma pẹ pupọ ki o to de o. O ti pẹju fun onjẹ, ati wipe onje si ti tan patapata nilẹ ti iwọ yio jẹ? Nigbana ni o tun tan Ọmọ aguntan na pada lọ si idi igi na lati tun fi iwo omi rẹ pamọ nigbati ọmọ aguntan si tun ma fi pada de o tun pẹju fun onjẹ o si lọ ṣun lai jẹun alẹ ọjọ na ti o fi lọ si ori akete rẹ lọṣun pẹlu ebi ninu ni ọmọ aguntan na fi sun lọ. bamubamu.

Li ọjọ keji ki onjẹ to setan adan, tun ko iṣe rẹ de o tun ran ọmọ aguntan lọ mu iwo omi na wa. nigbati nwọn si gbe onjẹ wa adan tun fi ọkanjuwa jẹ gbogbo rẹ tan. O ṣe eyi fun ọjọ merin titi ọmọ aguntan fi di atẹrẹ, ti o si ru ni ọjọ keji adan pada lọ sile ọmo aguntan si ru ẹru rẹ.

(Koiti pari)

---

## E MA KA

IWE IROHIN

ELETI-OFE

LỌSỌSẸ

O KUN FUN

IROHIN ALADUN

---


25th Anniversary

Exciting! BARGAINS

24th Oct. - 4th Nov.

Start Today

Amazing Offers . . .
must visit and we assure you of genuine reductions and better bargains . . .

ONLY 200
PILLOW CASES 2 3d

COLOURED
BED SHEETS 8 6d

WHITE
BED SHEETS 12s

ONLY 100
BRASSIERES 3s 6d

PLASTIC
FLOWERS 2s each

LEATHER Lot To
HANDBAGS clear 50o/o Off

GLASS Limited
TUMBLERS Quantity 6d each

BEER
MUGS 1s 6d
(GLASS) each

MEN'S LEATHER
SANDALS 21s pr.
(MADE IN FRANCE)

CHILDREN'S
SHOES 9s pr.

PLASTIC COVER
FOAM 3s 6d
RUBBER SEATS

STEEL
TRUNKS 50o/o off
SLIGHTLY DAMAGED

Remember

From TODAY 24th to the end of the month

We Are Open..

ALL DEPARTMENTS
8.30 a.m. - 12.30 p.m.
2.00 p.m. - 7.00 p.m.

SUPERMARKET
2 COLD STORE
8.30 a.m. - 7.00 p.m.
(no break) as usual
FOR
BEST
BAGAINS

Bhojsons

OYINGBO, EBUTE-METTA.


---

No 151

## Indenpendence Celebrations Office

### TENDER.

1 Tenders are invited by the Independence Celebrations Officer for the supply of three and a half million small National Flags of Nigeria to the following specifications :-

(a) Each flag to be nine inches in horizontal lenght and six inches in vertical length, excluding the hem for the stick.

(b) Each Flag to be in Nigeria's National colours, i. e. to be divided vertically into three equal part; the centre part being white and the two outer parts being green The shade of green is variously described as :-

(i) Under British Standard No, BF-2660 of 1955 it is chart 0-0-010.

(ii) Under the British Colour Council it is classified as CC104-CC105.

(iii) Under SILOR international colour chart it is classified as 193-173.

(c) The Flag should be made of plastic material or of a mixture of plastic and some other material.

(d) The colour dyes should be fast.

(e) The flag should be securely fastened to a stick approximately fifteen inches long.

2 Delivery will be made within five months from the date contract is awarded.

3 Tenders should be enclosed in sealed envelopes: " Confidential - Tender for Flags, " and should be accompanied by samples, so as to reach the Independence Celebrations Officer, 34-46 Ikoyi Road, Lagos, Nigeria, by noon on the 30th November, 1959.

4 The Independence Celebrations Officer does not undertake to accept the lowest, or any tender.

I. C. O.
16. 10. 59.

---

## Eni To Daruko Dan Fodio Wo Itimole

KAURA NAMODA. Ọmọ ẹgbẹ Action Group kan ni awọn Hausa gbe ju si itimọle nitoripe ọkunrin na nsọrọ nibiti nwọn nsọrọ ilu, o darukọ Ṣehu Dan Fodio.

Ọrọ pataki ti okunrin ti o njẹ Malam Ṣabi Bankọle sọ ni wipe, awọn Hausa nkegbe wipe ki nwọn dibo fun wọn lorukọ Ṣehu Dan Fodio, ki nwọn maṣe da wọn lohun,

Eyi ni ọrọ ti Ṣabi sọ ti awọn yandoka de, ti nwon si ti mọle.

---


M.B.T.

(MAGIC BLOOD TONIC)



Iná dé, òkùnkùn parẹ́. [illegible] dé, òkùnrùn jẹ̀ lọ. Ẹ̀jẹ̀ [illegible] òyì pọ̀ṣẹ̀ṣẹ̀. Àlá burúkú [illegible] àìlèsùn rẹ̀hìn-ẹ̀kún. M.B.T. fògùn-ẹ̀jẹ̀ ti nmú ní jẹun [illegible] amú ni yàgbẹ́ bi òkùn, [illegible] àkèré. Abíwẹ́rẹ́ [illegible] fawọn abiyamọ. [illegible] ati àìyà-jíjá ko [illegible] pẹ̀lú [illegible]

ARADAN STORES P.O.Box 2
EBUTE-METTA.


Printed & Published by The Union Printing And Publishing Company 28, Kosoko Street, P.O. Box 47 Lagos, Phone 23370.